ASOJE ORO

Olore ko ni ku, olo-
ore o ni run, 'gba
olore ko ni fo, awo
olore ko ni tu. atepa
oje atepamose kujo
kujo, kujo ore, towo
kome lo nyale olore.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO-ṢE WI LẸJỌ

OWE YORUBA

Nibiti o wu efufu lele
 odari gbe si, ibiti o
 wu olowo eni lo
 tan ni lo. Afefe le
 oni ori igi yeriyeri efu
 fu lo ole ori agbon
 woroko. Aja ko ngbe
 e olore. Aguten ko
 gbagbe eleri bore.

VOL. XII No. 667. LAGOS, SATURDAY, MARCH 19, — MARCH 25, 1960. KỌBỌ MEJI (2d)

# Padi Kan Wo Ewon Odun Gbere Nitori Oro Iselu

CHINA. Iyalẹnu nlanla li o jẹ fun gbogbo awọn Kenia paapa awọn ti nwọn nsin ẹsin aguda, nigbati a gbọ wipe awọn Ijọba ilẹ China ni apa ilẹ awọn "Ijọba l'o ni ohun gbogbo (Communist) lọhun ju Alufa Padi awọn Aguda kan si ẹwọn ọdun gbere.

Kini Alufa na ṣe? a gbọ wipe, nitoripe nwọn fura si Alufa na wipe o nda si ọrọ ilu wọn ati wipe o nṣatilẹhin lati da ori Ijọba ilu nja kodo, nitori ki Ijọba ilu na ba le ṣubu. Orukọ ti a gbọ wipe nọwn npe Alufa Padi ni Cookey May.

## AWỌN ẸGBẸ MẸṢỌ NṢE NKAN

EKO. Awọn ẹgbẹ kan wa ni Eko ti nwọn npe ni Mẹṣọ gbogbo awọn ẹgbẹ ti a wi yi jẹ gbajumọ, Sanmori, bọrọkinni, nwọn jẹ obinrin ti awọn ọkọ wọn p'owo ti awọn ọkọ wọn na si jẹ enia jankan-jankan larin ilu.

REDUCE FREIGHT RATES ! ! !

Your business will benefit in

1960

by using the Railway

A special rate of only 34/- per ton has just been introduced for ALL commodities from

Lagos, Apapa, or Iganmu
to
OSHOGBO

Previously you paid between 36/- and 181/- per ton for your goods,

save money now by using rail transport which is save and reliable.
the Best way is the Railway.

HAVE YOU ANY TRANSPORT PROBLEM ?

IF SO, CONTACT OUR
RAILWAY LIAISON OFFICER,
TEL. LAGOS 44245.

"Awon 'lo ranse aso kan lati ilu Oyinbo lati fi se awuyewuye odun awe, awon npe oruko aso na ni Ọle nrunmu.

Wawo bi awon 'ogowere gbajumo Eko ti nsare, ti won si oro gidigidi lo ra aso "Ole nrunmu" yi lati fi da buba, o le alago nla, opa re kan se opa aso meji (36ft.) ponun merin abo ni won nta opa kan.

Die ninu awon ti o nta aso na niwonyi: Amuda Grillo, Sidikat Arre Mundia Offin, Agbira Ewunu Brown, H. M. ati Mama Hakeem.

## ENIA AGB GBE IWỌ-ORUN RỌ SI AIYE IDẸRA.

IBADAN Irohin tẹ wa lọwọ lati Ibadan wipe oloye S. L. Akintọla se idande owo ori fun gbo gbo awọn ti o ngbe agbegbe Iwọ-orun, o si fi ẹgunlọgọ owo ori jin wọn.

Oloye S. L. Akintọla sọ wipe enia ko le se alaisan owo ori kan-kan, nitorina owo ori ti on palaṣẹ ati eyiti on bu fun gbogbo enia lati ma san lọdọdun ko gbọdọ tayọ £1 : 17 : 6, enikẹni ko si gbọdọ gba iye owo ti o tayọ eyi tabi ti o le lori eyi lọwọ enikẹni.

O tun sọ wipe, awọn igbimọ ti nwọn ba gbowo ori yi ti ko si to iye ti nwọn ti ngba latijọ, Ijọba Iwọ-orun ti se tan lati fi ara din eyiti o ba din ninu owo awọn enia na.

Ogbẹni Alatako kan ti o njẹ Tabiowo sọ wipe Ijọba Iwọ-orun ti mbu owo danu nipa sisan egberin ponun fun owo ile ti Oloye Awolọwọ ngbe, Oloye Akintọla dahun pe bẹni ọrọ na ni tọọ ise bere ni eyi ,e lara ti awọn Hausa ti nwọn fi ẹgbarun Ponun kọ afin ti Sardauna yio gbe.

Ogbẹni A. O. Adingboye sọ wipe, ẹjẹki ẹ... ninu awọn Ij... ba... ... ... lati daa ... ... ... dawo yi lasi ki awọn ... ... ori agbegbe won ku, ti nwọn wa wo bi jabe-la ti aji ... lati.

Awọn ẹgbẹ N. C. N. C. ti nwọn nkebosi pe owo ori ni sisan poju nile Yoruba, owo ori tiwọn niyi: Enikọkan ... ni lati san ọgbọn sile fun ilu ti o ngbe, sile mẹdogun fun owo ori pelu ainiye owo ẹkọ ati owo pẹpẹpẹ miran ti nwọn ngba.

## ILA-ORUN PINNU LATI DAWỌ AFỌWỌRA DURO

ENUGU. Ijọba Ila-orun Ilẹ Nigeria se ipinnu wipe, bi oti wu ki o ri awọn yio sa gbogbo agbara wọn lati ri wipe, won pano iwa afowora ninu Enugu larin awon enia ti e n ji awon eru Ijoba ko lo, ati iru iwa buruku ti awon enia ma nku lati ma tu awon oro asiri ti Ijoba ba so.

Ogbeni J. O Udosi so wipe idire ti Ijoba se fe gba ona yi yo si awon alafowora na ni wipe lenu ojo die yi, opolopo ninu eru Ijoba ni won ti se afowora gbe lo gege bi Typewriter, ero ifatagun si ara, ti a ngbe ka ori tabili, awon aso tawęli ti a fi nnuwo nigba aba fi omi we owo, ati awon ti o nlo ji keke Basikulu awon osise.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

### HIGH VOLTAGE SWITCHBOARD

The Electricity Corporation of Nigeria invites Tenders from responsible Contractors for the supply of the following c.i.f. Port Harcourt:

1 No, 8 Panel Switchboard fitted with 5 Solenoid operated oil circuit breakers insulated for 11 kV having a minimum fault rating of 250 MVA at 6600 Volts.

On payment of a deposit of £5., tender documents comprising Tender Form, Specifications of the Contract, etc., may be obtained from The Secretary, Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarters, 13, Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential Tender for the supply of Aba Switchboard" and must be received at the office of the Secretary not latter than noon on 23rd April, 1960. Tenders received in any other manner will not be considerd.

On receipt of a bona fide Tender the the £5 deposit will be refunded The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any Tender.

Further information concerning this Contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer, at this Headquaters

C.K.O. Adenaike

Acting Secretary To The Corporation


---

**TOWN COUNCIL FI KUN OWO OMI EKO** Eko. Igbimo Lagos Town Council se afikun owo omi ilu Eko ni sile lori posun kan yio si bere lati ibere osu April 1960.

Ninu ipade ti awon ti ro oro yi die loku, igi gangan-ran fere gun orun loju larin awon egbe N. C. N. C., ati omo egbe Action Group, ni toripe bi A. G. ba taku wi pe, bayi ko dara, awon N. C. N. C yio wipe beni awon fe.

---

## JORA ILE GHANA SO WIPE FARANSE BA ILE WON JE.

Ghana Ogbeni AlexQuaison ti ise asoju ile Aganyin ninu egbe Maj, obaje so wi pe adehunbo etu oloro ti gbogbo aiye se arowa fun Ijoba Faranse pe ki awon mase yin sugbon ti awon fi r kunk un, ati iwa tani yio mu mi yin eti na ti ba gbogbo efufu ile ghana je.

Iru bombu ti etu oloro na da sile ni ile Ghana, ako ri iru re ri ko si eniti ole so ohun ti atun botan etu oloro na yio yori si, tabi iru nkan ti yio da sile.

Nitori iru nkan bayi ni Ijoba Ghana se funka mo gbogbo owo ti adotalerugba oke Posun ati ati dukia won ti o mbe ni Ghana nitori ki won le ri owo sanwo fun awon ti o ba se ori buruku se alabapade efufu buruku na at awon ti dukia won ba baje ni efufu yi.

# Itan Bi Hausa Ti Se De Ariwa

Apa III

Lati owo B. A. CAREW

Bayajida, jagun-jagun alagbara ni, segun ejo inu kanga yi, o ke ori ejo na o so sinu apo ikopa re. Nigbati ile mo, okiki ta, gbogbo ilu nro wa lati ri ohun iyanu ti o sele. Bayi ni irohin kan Daura, obinrin to nse oba ilu na.

Bi irohin ti kan oba yi inu re dun to be ti o fi dide ti o si mura ola jade lati lo wo ohun ti o sele. Nitoripe ejo yi ti wa nibe fun odun gbooro ti ko si akoni okunrin kankan ti yio ko lo ja.

Oba dahun nigbati o ri ise oyanu nla yi pe, Emi yio da ijoba mi si ona meji fun eni na ti o pa ejo yi.

Nigbati okunrin kan gbo bayi o fo jade o si dahun pe, "Emi ni mo pa ejo na" oba bere lowo re pe ki o mu ori ejo na wa ki on wo. Okunrin na ko ri ori ejo mu wa.

Irohin kan iya arugbo ti Bayajida wo si ile re pe oba awa eniti o pa ejo inu kanga lati da ni ola. Iya yi to oba lo, o si so fun pe on mo eniti o pa ejo na.

Iya arugbo yi rohin fun oba ati awon igbimo bi okunrin yi se wo ilu ni Oru, ti obaba orugbe mu on ati eranko re.

Alaye:- (A pe esin ni eranko ni ilu Daura nitoripe a ko ri esin ri, bi ko se eyi ti Bayajida gun wa la fi se akoei)

Iya na si fi han oba bi on ti se kilo-kilo fun u pelu alaye ohun ti o se ti a ko fi le ygu omi mu a fi bi ojo ke'e ba pe.

Oba ni ki iya pe alejo re wa. Nigbati alejo yi de, o bu ola fun oba gidigidi, o si wi fun oba pe on ni o pa ejo inu kanga.

Oba bere ori ejo na, okunrin yi na fun u. Oba dupe lowo re pupo fun igbala ti o se fun on ati awon ilu na.

koiti pari

---

# Jamba Ile Jamba ode, oluwa mafi Jamba se wa·

Lati Owo CAREW (Apa 11.)

Erukunrin yi je iranse lasin oko ati aya l'arin ile ati ni ita. Ni gbogbo igba ni on pelu olowo re nlo si ode, ko ba se oja rira l'arin ilu.

Gege bi omo odo aye wa fun lati ma ba iyawo olowo re yi ohun pada. Nigbati o se, ti oro kon oro ni ojo kan, o so fun iyawo olowo re se, ko damiloju se oko re feran re gege bi o ti nife obinrin kan ti a jumo nlo si ile re.

Iyawo olowo re fa mora, o tu u loju kio le so obinrin na kio juwe re, tabi kio so oruko re fun on.

Erukunrin yi da-hun wipe on ko ni so oruko re beni on ko ni juwe re; sugbon on yio se iranlowo fun o nipa egbogi ki oko re le da oju ife ko iwo nikan ju ti enikeni lo. Iyawo na dupe gidigidi fun iranlowo ti eru yi mura lati se fun.

(Woyoku ioju ewe keje)

---

# Ipade Alafose Ibadan Ati Onigbetu-gbetu Ejigbo.

Ni ojo kan, Alafose Ibadan nkoja lo silu Iwo, o ri ba Onigbetugbetu kan ti o nlo silu Ejigbo, awon si mba iris ajo won lo. Bi awon ti nlo loju ona, Alafose ri okun owo be, osi ko lati fun Onigbetu-gbetu ninu re.

Nigbati awon de ilu Iwo nibi ti awon mejeji yio gbe pinya, Onigbetu-gbetu kigbe mo pe gbe owo mi wa, ki o fowo fa eti re ki o si ma sare lo. O si se be.

Nigbati ojo re wale tan lo ba lo rohn fun Oluwo nipa nkan ti okunrin na se fun u. Sugbon epe ko boro mo

# Ikede PataKi

A fi wosika wa ọṣẹ yi ke si ẹnyin Ọkawe wa ti o nbẹ ni Oke-okun (Ghana) wipe ki ẹ fi orukọ awọn ọrẹ nyin ti o nka iwe irohin ni ede Yoruba ranṣẹ si wa ki a ba le ṣe eto lati fi iwe irohin Eleti-Ofẹ ranṣẹ si wọn.

Ẹniti o ba fi oruko enia pataki mejila ranṣẹ si wa ti wọn si sanwo iwe wa silẹ fun ọdun kan ṣandi a o fi iwe irohin Eleti Ọfẹ ranṣẹ si oluwarẹ fun oṣu mẹfa lọfẹ.

Olotu.

## Itan Ogunbebe ati Ajantiele

Lati owo Ẹao
(apa 2)

Ni akoko kan ti awọn irunmolẹ ma nlọ daurawo leti okun nipa biba ara wọn ja igba, Ogunbebe jẹ obinrin, ko si le ba wọn ja igba, ṣugbọn o feran awon alagbara.

Bi Ogunbebe ba nlo woran ere igba, ama gbe oyin ati apere eko kan dani, awon ti oba ja nigbati awon ba si la enikeji mole, Ogunbebe ama fi oyin fo ẹko tutu fun won.

Ajantiele je mole kan ti o lagbara, ti o si je igiripa, ako si ti gbo pe enikan fi ehin re bale ri ayafi mole kan ti won npe ni Onituupulu. Nigbagbogbo ni Ajantiele ma nda won ni igba ti a wi yi. Iru agbara ti Ajantiele yi mu ki Ogunbebe gba ife fun.

Nigbati odi odun keji ti won ti nfẹ ara won Ogunbebe bimo okunrin kan fun Ajantiele won si fun omo na ni oruko Olujebete, osi ko ise oogun ati ode igbo, nigba gbogbo lo n tele baba re lo woran igba.

(koiti pari)

Accountants. The English & International Society Admission on Professional Experience.
9, Charles St. Newport. Mon,
England"

## Itan Anobi Liasu

(apa 9)
Lati owọ Lemọmu Ajakuta

Lẹhin ti iyan ti kasẹ kuro nilẹ ni Olorun so fun Liasu wipe akeko rẹ to ti o nilati fi ile aiye silẹ, nitorina, ki o ma niṣo lori oke kan ti o mbẹ ni irin ọjọ mẹta si Jerusalem. Bakanna ni Olorun tun sọ fun Anabi Masu ti o jẹ ẹa-abe tabi iranṣe Anabi Liasu pelu.

Anabi Masu wa pinnu lọkan rẹ wipe on ko ni jẹki ọga on mọ. Bi akoko ba to lati gokẹ lọ si ọrun bi on ba di mọ, daju wipe on pelu AnobiLiasu ni yio jijọ wọ ile Alijọnnu lọ. Nitori idi eyi o bere si sọ ọga rẹ lọwọ ati lẹsẹ. Bi Anobi Liasu ba gbe ẹsẹ mẹta, Anọbi Masu yio gbe meji.

Nigbati Anọbi Liasu de ori oke beni ẹfufu ajija de, o bere si yika Liasu ati Masu, Anọbi Masu yara dimọ aṣọ alikimba ti Anọbi Liasu gbe wọ, o si kọ lati ju silẹ, nigbana ni Ọlọrun sọ fun Liasu pe ki o bọ alikimba re silẹ fun Masu. Ni Liasu ti bọ alikimba na silẹ fun Masu, beni ẹfufu ajija ba gbe Anọbi Masu jina rere si Liasu pelu ẹwu alikimba lọwọ rẹ. Beni awọn Aliburaki meji de nwọn si gbe Anọbi Liasu nikan goke lọ si ọrun laye.

Koiti pari

## Mo gbontan Momotan

(Apa keji ii)

Oyin de iwaju Ẹlẹda o kii e si bu Ọla fun u bi o ti tọ ati bi o ti yẹ. Ẹlẹda bere lọwọ oyin pe kini o nfẹ. Oyin dahun tọwọ-tọwọ pe on fẹ lọ sinu aiye.

Ẹlẹda bere lọwọ rẹ pe kini iṣẹ ti o fẹ ma ṣe nigbati o ba de aiye. Oyin dahun pe on fẹ ma ṣe oro ti a npe ni Oyin igan.

Ẹlẹda sọ fun u, awọn nkan ti o ni lati ma toju silẹ ati ọnati yio ma fi po wọn pọ ati akoko ti o ni lati ma jẹki o wa ni isinmi ti yio fi di oro.

Oyin fi ara balẹ gbọ gbogbo rẹ. Eyiti ko ye e to daradara o tun fi ọgbọn ati suru bere lọwọ Ẹlẹda, ẹniti o fi gbogbo rẹ ye e yekeyeke.

Nigbati oyin gba gbogbo ẹkọ yi tan, o dupẹ lọwọ re o si jade kuro ni afin Ẹlẹda lati lọ palẹmọ lati wa si aiye.

Ẹnikeji ti awọn iranṣe pe lẹhin lati lọ si iwaju Ẹlẹda ni Agbọn. Agbon ki Ẹlẹda bi o to ati bi o ti yẹ. Ẹlẹda bere lọwọ agbọn pe, "Kini o fẹ".

Agbon ni "Kabiyesi Mo fẹ lo sinu aiye lati ma lo gbe aiye" Ẹlẹda tun bere pe "Kini iwo fẹ lọ ṣe ninu aiye?"

Agbọn ni "Kabiyesi mo fẹ ma ṣoro nigbati mo ba de aiye."

Ẹlẹda wa bere lati ma la ye e ọna ti yio ma fi ṣe oro gẹgẹbi o ti la ye oyin ti o ko wa si iwaju Ẹlẹda.

(Koi ti pari)

Kere o !

A ti ni orisirisi egbogi fun arun Inarun ati arun Jẹdijẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, l'ọkunrin ati l'obinrin ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHRES

MEDICINE STORE

7, Egerton Road, Lagos

## MABADEJẸ NI OYE ALAIYE ODE KAN.

IJEBU REMO. Awon egbe Adepeju ni agbegbe Ijebu Reme, ti kowe si Ogbeni Olola D. S. D. Adegbenro wipe Omoba Mabadeje Sotinwa ni eniti awon yan lati je oye Alaiye Ode Reme.

Awon egbe na so sinu iwe ebe won wipe, awon fe ki Ogbeni Adegbenro tete bu won yenju oye na ki won le fi eniti awon ni yi loye na, pelu irorun ati pe ki ilu le roju.

## Ile ko lati sujada fun orun (Apa 3).

lati owo Eso

Ọrunmila wa yan ẹbọ fun araiye [illegible] Olodumare, araiye gbọ nwọn ko bọ awon si setutu. Nigbati Olodumare [illegible] bọ na, o wipe mo sebi ẹ sọ fun mi pe ile kọ lati sujada fun Ọrun ni bo ni ẹbọ yi ti wa.?

Olodumare wa yan awọn Molẹ meji awọn lati lọ ṣe [illegible] ile ati ọrun wa, nwọn ni ki Aajo lọ sile aiye lọ gbọ ọrọ araiye (eyi nidi rẹ ti awọn baba wa ṣe nfi obi ajopa ṣe ipari ija). Nwọn ni ki Abẹmọ lo wadi ija na lọdọ ara ọrun.

Idi ija yi ni awọn mejeji lọ wa ti awọn araiye ko le fi ṣe suru rọ gbogbo awọn ọdẹ aiye ṣigangan, nwọn nlọ wa eku ẹmọ lati pa lati lọ fi bẹ Ọrun ki o le sọ idẹra kalẹ fun araiye. Aṣe bi a ti nṣe laiye beni awọn nṣe lọrun, Awọn ọdẹ tun nmura lati lọ de igbo molẹ pa ẹmọ bayi ni ọdẹ aiye pade ọdẹ ọrun lẹnu ala ile aiye ati ọrun.

(Koiti pari)

POLOWO OJA RE SINU IWE ELETI-OFE L'OSOSE

# ELETI-OFE

A-NIU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos — P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM — "ELETI - ỌFẸ, LAGOS — Phone 23370

OL. XII. NO. 667. SATURDAY MAR. 19 — MAR. 25 1960


# Idera De Sile Iwo Orun

Ọlọla Oloye S. L. Akintọla ti iṣe Olori Ijọba Iwọ-orun ni a ṣe ipade apọnle eto isẹ rẹ ti o pinnu lati ṣe si ipinlẹ Iwọ-orun fun anfani gbogbo enia l'ọkunrin l'obinrin, olowo ati mẹkunnu fun adinku owo ori, eyiti awọn obinrin ko tilẹ ni san mọ rara ni agbegbe Ijẹbu ati Abẹokuta, gẹgẹbi ọrọ owo ori na ti jẹ ohun ti o nfun awọn enia ipinlẹ na ni aifayabalẹ lati le gbe inu ilu pẹlu igbadun.

Aṣe kekere tilẹ ni ikede ti a kọkọ gbọ nipa ti owo ori na, eyiti Gomina Iwọ orun tun sọ ninu ọrọ rẹ lati ori aga-ọla ninu ile igbimọ Aṣofin ti nwọn bẹrẹ ninu ọsẹ yi tun pa hamhari, nitoripe, o tun fi han siwaju wipe gẹgẹbi ijọba ti gbero lati ṣe eto owo ori gbigba ni ipinlẹ Iwọ-orun yio mu idẹra ati irọrun wa ju bi a ti lero pe yio mu lọ. Ati paapa awọn ti o jẹ mẹkunnu enia ti ko ngba owo pupọ lenu iṣẹ wọn, owo ori ti nwọn yio ma san ko ni mu inira wa, nitoripe awọn ko ni gb'owo ti o ba ga ju eyiti agbara olukuluku enia ba ka lọ lati san fun ijọba.

Lori eyi, enikẹni ni yio da muso fun Ọlọla Oloye Akintọla pẹlu orin idunnu ni kikọ bayi;

> Idẹra ti de, ti de, ti de,
> idẹra ti de fun wa
> ni ipinlẹ yi o he e!.


ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣokun oju, gbgihon ọwọ, ailesun, ailokun ninu ti irufẹ arun bawọnni. O je ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na can ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

The Egba Trading Aradan Stores 12, Denton Street. 18, Denton Bridge Street. P O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.





## OLUWADI AWỌN OHUN IṢẸDALẸ RI ERE ABAMI KAN.

JOS. Ọgbẹni C.P. Thurstan Shaw ti iṣe okan ninu awon ohun iṣẹdalẹ enia dudu, wale



titi o kan ere abami kan o sọ wipe lati igbati on ti nṣe ni Cambridge on ko ri iru ere bi iru eyiti on ri nilẹ Nigeria yi ri.

O so wipe on lo gbẹlẹ ninu igbo kan ti nwon npe ni igbo nla ni agbegbe Ila-Orun, on ri ere kan ti o jo on loju pupọ. Idi rẹ ti ere na fi jọ on loju ni pe, o yatọ si gbogbo awọn ere ti on ti nri ni ilẹ Nigeria. Oluwadi na sọ wipe awọn ere ti on ri na fẹrẹ jọ ti ọba kan ti nwọn npe ni ọba Nri ti o ti wa nilu kan ti a npe, ni Ori Eri on si lero wipe nwọn ti ri ere na mọlẹ ni igba ọgọrun ọdun 1600-1700 A.D. Ere ti a wiyi wa ninu ile awon oriṣa tabi ninu ile ibiti a nfi awọn ohun iṣedalẹ pamo si nilu Jos.

Ere ti a nwo aworan rẹ loke Iwe yi jẹ ọkan ninu ere ti nwọn hu jade nilu Jos.







# Awon To Lo Ko Eko Ogbon Ori



Awon omo ile Nigeria meji ti a nwo yi ni awon ti o gba ẹko olofe lo lati koṣe ogbon er nlan College kan nigboro ilu London.
Ogbeni Nkanu Esege lowa ni apa otun, Ogbeni E. A. W. Fajemisi lo wa ni apa osi.

## IGBEYAWO OMOBA KO DIWỌ LATI WA SILẸ NIGERIA.

Ọba ilu Oyinbo, Elisabeth Keji ti sọ wipe nigba ominira ile Nigeria ni odun 1960. osu October, aburo on ti o jẹ ọmọ baba on ati ọmọ iya kanna ni yio wa s ile wa lati ba wa yọ ayọ ominira.
Sugbọn irohin de etigbọ wa wipe ọmọba Margaret, nfẹ gbe iyawo ninu osu May ti o mbọ yi.
Ibẹ ni ariyanjiyan ti wa dide wipe ojẹ yio wa bawa sẹ ajọyo Ominira ichin ti o ba ti di abilekọ tabi ko ni wa mọ?
Idile kan ninu awọn idile ọba Gẹsi ti awọn npe ni idile Clarence fi ye gbogbo aiye wipe koiti fi si ay padi ninu gbogbo eto ti ati se sile fun lati wa ṣe aṣoju ọba nilẹ Nigeria lasiko Ominira ilẹ Nigeria.
Alhaji Tafa Balewa, Prime Minister ilẹ Nigeria so kọkọ fi oro yi han ninu igbimọ nla ( House of Rep ) ni ọjọ 12th osu February 1959, pe Ọmọba Margaret ni yio wa ṣe aṣ oju ọba ni 1st Oct, 1960.

# Aliyu Lo Keko Ise Ero



Eniti a nwo ti o duro larin awọn eni meji nwọnyi ni Ogbẹni Aliyu Osọbebe Ogbori ti o kọ ẹkọ nilu Oyinbo lati ilu Eko.
On lo sikọta awọn tinwọn lọ kọ ẹkọ ninu Heriot Watt College nibiti awọn nkọ iṣẹ ẹrọ afowo ṣe

## OJA EREKO DI ATUNKO FUN AWON ALASO NYLON

EKO. Oja ti o wa niwaju petesi Kora Aliyu ni Ereko atijọ ati eyiti o mbe ni egbe Mosalaṣi ti o koju si ile egbe Tom Jones ni oja kanna yi nibiti awon obinrin oloja gbe fi se ibuso aso Iylon, ti awon Igbimo Lagos Town Council wo lule nitori oro ilu lo tun ta'siwa leti fereṇ wipe, Ogbeni F. S. Macewen ti o je alaga igbimọ na ti fi ase si wipe, ki won tun gbogbo awon iso na ko, ki won si da awon obinrin oloja ti won ti le kuro nibe pada si aye won.

Agbo wipe, ki eto di wipe a won iso na di kiko pada, ọro na gba odo, o gba olo tobe ti egbe wipe egbe N. C N. C. ati egbe Action Group gbon omi ju ara won loju, ki Ogbeni Macewen to pase fun Ogbeni Mayaki wipe ki o se eto lati lati lọ tun awọn iso na ko. Ki Ogbeni Mayaki si ri wipe awon ti o ti ni iso na lakeko ni won gbe iso na fun, Ibaje omo egbe N, C. N. C. lo l tele ri on ni won gbe fun, bi oba si je Action Group ni, on ni ki won gbe fun.

## IJỌBA NIGERIA KỌ ẸKỌ ỌLỌFẸ ILẸ EGYPT

A gbo irohin wipe gbogbo awon enia, marun ti nwon se ezire lati lo ko ẹko ofẹ ni ile Egypt lodun to koja lo ni ijoba ko fun wipe nwon ko le gba won laye lati lo ko ẹko nilẹ Egypt.

Ọkan ninu awon omo akẹko lo wa ro fun awon Oniwe irohin bayi pe: Lodun to koja lo ijoba Egypt kowe si wa pe nwọn ti gba fun wa lati lo ko eko nilu Cairo. (Egypt lofẹ ni university of Cairo.

A si lo lati gba iwe ese fun irin ajo wa awon alaga ibẹ so fun wa pe, bi aba se lo si ibẹ a ni lati fi se wa sile na, a si se bẹ. Lẹhin ti a se bẹ tan ni nwon tun so fun wa pe ijoba apapọ tile Nigeria ko gba lati fun enikan ni iwe ese lo si ilẹ Egypt.

(Wo yoku loju ewe keje)

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Twisted Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Send Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 421 Archway Road, London, N.6, England

## Oj[illegible] nse Og[illegible], ara Ogun ko le, oko Oba nse aisan

London. [illegible] Prince Phillip, Duke of Edinburgh [illegible] o fi ara sile ko le [illegible] jade wa lati afin oba. Duke [illegible] Windsor Castle, [illegible] Ob[illegible] [illegible] Ajode ara yio ma jo o.




EBUN ILERA



Ara-lile, agbara ati okun-inu ni ișura ti o koja idiyele, awon ẹbun ẹda ti o dara julo ni Ko si ounjẹ miran ti o nfun ni l'okun-ilera etata bi Ovaltine, ohun ti a fi peelo re ni ounjẹ atẹjẹșe ati eyi ti o nfun ara ni okun. Mimu Ovaltine lojo-/umo ni ona to dara julo ti o si rorun julo lati fun ni ni opolopo ilera ti o dara tele, lati ri i da-ju pe a ni okun lojojumo ati idera, orun asun-wora. Ẹgbẹgbẹrun awon olomode ni awon mo anfani atata ti Ovaltine ni, ounje olomi ti o j da-ra julọ.




## IJOBA NIGERIA KỌ ẸKỌ ỌLỌFẸ ILẸ EGYPT

Omọ akeko na so pe, awọn tun ko we pada si Ijọba ile Egypt nipa ohun ti Ijọba Apapọșe ilẹ Nigeria șe fun won, Ijọba ile Egypt tun kọwe si won pe, ko buru awon furra won yio kọ we si Ijọba Apapọșe tilẹ Nigeria. Eyi o ri pe iya meji je akura, ẹke ti won fẹ lọ kọ ko bo si mo, nibiti awon gbe ọsẹ ojo won awon padanu rẹ.

## JAMBA ILE JAMBA ODE OLUWA MA FI JAMBA ȘE WA

(obere loju ewe keji)

Ọkunrin yi di ọmọ kikẹ ati ọmọ gige l'ọdọ iyawo olowo rẹ nitori iranwọ pataki ti yio șe fun u, papa julo, o fere da ni amoron pe ki ọkọ rẹ ṣọ di ọmọ Ṣegbọn jamba ile ni ọrukunrin yi npa lepe si ile fun iyawo olo-wo rẹ.

Atoro adurr fun awọn ẹka-we yi peki oluwa rere gbawa lọwo jamba ile pẹlu t'ode';

Gẹgẹ bi ara awon ara ilu yi, nwon ama sa ba gba atẹgun lẹhin agogo meji osan ninu ẹhi-nkulẹ nwon, nwon a si ma fi orun diẹ ra aju di ẹhin agogo mẹrin.

Nigbati o ya erukunrin yi lati gbe iwa rẹ jade, o pe iyawo olowo rẹ, o si so fun pe, ni Ọla, emi yio so ohun ti ao șe un o.

Ni ojo keji, ope iyawo olowo rẹ, o so fun pe emi yio mu abe ifari wa fun o li ojoro, ti o ba di osan ola, nigbati bale re ba sun ni osan, ki o fi abe na fa irun odo agbon re wa, emi yio fi șe awure ifẹ fun ọ.

Ha! iwo aso irun pọ mọ ti ipako, oro nba ọ wi, ki o tẹ eti re sile tabi ki o fi eju re ka iwe yi.

Ọrukunrinyi ti o fi okan iyawo olowo re bale pe on yio șe iran lowo fun, on kan na lo tun dide lẹhin igba ti o ti ta koko jamba rẹ tan, o lo so fun oko iyawo ti ișe olowo re.

we iyoku loju, ewe kejọ)

POLOWO OJA RE SINU IWE ELETI-OFE L'OSOSE

## Omidan Fi Alumogaji Se Eye Fun Omoba.



Laipẹ yi, nigbati ọmọba Margaret lọ si ile afihan ti gbogbo agbaiye, ibe ni ọmọge kan ti o njẹ Magna Abudlah ti fi alumọgaji ti awọn ti ṣe niwọn ogorun ọdun sẹhin ti o si mbẹ ninu ile Isura sheffield ta ọmọba na lọrẹ ninu Liverpool, Ẹniti o duro legbẹ osi ọmọba na ni Lord Home.

## Ijoba Nwa Okunrin to Fi Eru Wo Ile Nigeria

GUINEA. Adajọ kotu Eko paṣẹ wipe ki a lọ fi iwe ipa mu ọkunrin kan ti o njẹ Thomas Yousufu Njai ti o wa tun ijọba Nigeria jẹ wipe, on jẹ aṣoju ilẹ Guinea (Republic of Guinea) ṣu gbọn nigbati akaru lu sopo ti nwon si ranṣẹ lọ mu aṣoju ilẹ Guinea na, a gbọ wipe o ti salọ.

Ẹsun mẹrin pataki ti awọn ọlọpa ka mọ lẹsẹ ni wipe oba awọn kan ṣsopan pa po lati da ese arufin bur. nku kan, (2) Ola awọn oyinbo U. A. C. ti o nta moto ni jibiti nipa pipe ara rẹ fun wọn pe, on ni asoju ilẹ Guinea ni Ẹko.

3. Nitoripe o je alejl enia ti ko ni ase lati wo ile yi, o si fi eru wo ile Nigeria lojo aisun odun Keresimesi nipa be odi arufin si ofin amunimuye. (4) otun fi eru gba Ponun meji lowo ọkunrin kan ti o nje Gereme Akintunloye lati gba sibi ise gegebi akowe asoju Guinea.

### JAMBA ILE JAMBA ODE OLUWA MA FI JAMBA ṢE WA

(o bere loju ewe keji)

O wipe Olowo mi.. eti re melo, ni ọsan ola ti o be wọ agbala lati sin mi o kọ gbọdọ sun rara se mi ki n di oju rẹ ki o si pa rọrọ bi eniti osun.

Emi ri Iyawo rẹ ti o npon abọ ifari o si nsọ wipe ni ọla pẹlu ogo Ọlorun emi yio dunbu ọkọ mi. Eyi ba mi lẹru gidigidi nko si le fi si inu mi lai sọ fun ọ.

(Koiti pari)

POLOWO OJA RE SINU IWE ELETI-OFE L'OSOSE

Advert. No. 26

**PUBLIC HOLIDAYS, 1960.**

With reference to advertisement No. 26, published in this newspaper on the 14th of March 1960, the public Holiday in celebration of the Muslim Festival of Id-el Maulud this year will be Monday, September 5th and not on Monday the 6th of September.

**Bata**

**OPENING NEW SHOP**

**AT IBADAN,**

**47, Lebanon Street,**

**SPECIAL OFFER**

**3 Pairs Socks For Price Of 2 Pairs**

First 100 Customers 20 Percent Discount On Shoes.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street, P. O. Box 467 Lagos Phone 23370